# IṢURA INU OKO, PERLI OLOWO IYEBIYE, ÀWỌ̀N ẸJA

## Matteu 13:44-52

### Ẹkọ 78 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ofin ati awọn woli mbẹ titi di igba Johannu: lati igbana wá li a ti nwasu ijọba Ọlọrun, olukuluku si nfi ipá wọ̀ inu rẹ̀" (Luku 16:16).**

**I Iṣura ti a Rí nibi Ipamọ ninu Oko Kan**

1. Ijọba Ọrun dabi iṣura kan ti a fi pamọ sinu oko kan, Matteu 13:44; Kolosse 1:26
2. Ọkunrin kan ti o ri i fi pamọ nitori o ṣe iyebiye, Matteu 13:44; 6:20
3. O ta ohun gbogbo ti o ni lati ra oko naa, ki o ba le ni iṣura naa, Matteu 13:44; Luku 12:33

**II A Ri Perli Kan ti I ṣe Olowo Iyebiye**

4. Ijọba Ọrun dabi oniṣowo kan ti o n wá perli ti o dara, Matteu 13:45; Kolosse 1:26, 27
5. O ri perli olowo iyebiye kan, ti o ju gbogbo ohun ini rẹ̀ lọ, Matteu 13:46; Kolosse 2:3
6. O ta ohun gbogbo ti o ni ki o ba le ra perli olowo iyebiye naa, Matteu 13:46; Owe 2:1-5

**III Àwọ̀n Ẹja ti a Sọ sinu Òkun**

7. Ijọba Ọrun dabi àwọ̀n kan ti o kó oniruuru ẹja, Matteu 13:47; Isaiah 45:22
8. A fa àwọ̀n naa soke, a si ya ẹja rere ati buburu sọtọ, Matteu 13:48; 7:22, 23
9. Bayii ni awọn angẹli yoo pin awọn eniyan buburu niyà kuro lara awọn oloootọ nikẹyin, Matteu 13:49; 25:31, 32
10. Ni ọjọ idajọ a oo sọ awọn eniyan buburu sinu iná ileru, Matteu 13:50; 25:46

**IV Awọn Owe naa Yé Awọn Ọmọ-ẹyin Jesu**

11. O wà pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ nikan, lẹyin ti O ti tú ijọ eniyan ká tán, Matteu 13:36
12. O bi wọn leere bi o ba yé wọn, wọn si dahun pe, bẹẹ ni, Matteu 13:51; 10, 11
13. Awọn wolii kọ́ wa ni "ohun ti atijọ" ṣugbọn Jesu kọ́ wa ni "ohun titun," nipa Ijọba naa, Matteu 13:52; Luku 10:23, 24

## ALAYE

Ni akoko yii Jesu nikan ni o kù pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, nitori O ti tú ijọ eniyan ká, Oun si wọle lọ (Matteu 13:36). Nitori naa O pa owe mẹta wọnyii fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ nikọkọ. Ṣiwaju akoko yii awọn ọmọ-ẹyin ti beere lọwọ Rẹ̀ eredi rẹ̀ ti O fi n fi owe bá awọn eniyan sọrọ, O si dahun pe "Ẹnyin li a fifun lati mọ̀ ohun ijinlẹ ijọba ọrun, ṣugbọn awọn li a kò fifun" (Matteu 13:11). A le wi pe awọn ọmọ-ẹyin mọ pupọ nipa ohun ijinlẹ Ijọba na, nitori a tun wọn bi, akoko atunbi ni a maa n pilẹ Ijọba Ọlọrun ninu ọkàn gẹgẹ bi a ti kọ́ nipa rẹ̀ sẹyin (Luku 17:20, 21). Igbe Johannu Baptisti ni pe "Ẹ ronupiwada: nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀", eyi ni pe kò si ọna miiran si Ijọba naa afi nipa ironupiwada. Nigba ti Jesu si n ba Nikodemu sọrọ, O wi pe, "Bikoṣepe a tún enia bí, on kò le ri ijọba Ọlọrun" (Johannu 3:3). Itumọ ọrọ wọnyii ni pe nigba ti a ba tun eniyan bi, oun le riran, nipa bẹẹ o si le mọ daradara nipa "ijinlẹ ijọba na" ju bi o ti ye e lọ nigba ti o jẹ ẹlẹṣẹ. Nitori naa a gbagbọ pe Jesu n pa owe mẹta wọnyii fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ nitori wọn kun fun imọ ti o ga ti o si jinlẹ, nipa ohun ti Ijọba Ọrun.

**Iṣura ti a fi Pamọ**

A le sọ nigba naa pe "iṣura" inu oko jẹ apẹẹrẹ ohun iyebiye ti Ijọba Ọrun. A fi iṣura yii "pamọ sinu oko", kuro ni oju araye. Ṣugbọn "ọkunrin" yii ti Jesu n sọrọ rẹ **ri** iṣura naa nigba ti o ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ ti o si di atunbi. Oun ni a si fi fun lati mọ niwọn iba diẹ, ijinlẹ ti Ijọba naa, nigba ti o si **ri** iṣura naa, o yara fi i **pamọ** -- ki i ṣe pe o fẹ fi i pamọ ṣa fun aladugbo rẹ, nitori oun fẹ ki gbogbo aye mọ nipa iṣura yii; ṣugbọn o n gbadun rẹ̀ ninu ọkàn rẹ̀ gẹgẹ bi ohun ikọkọ ti o jẹ pe awọn ẹni irapada Oluwa nikan ni o le mọ ọn. "Nitori ayọ̀ rẹ̀" (ti o fi hàn pe a tun un bi); eyi mu ki o lọ ta ohun gbogbo ti o ni lati le ra iṣura iyebiye yii; nitori o ti ri i daju pe o niye lori ju ohun gbogbo ti oun ni lọ.

Ọlọrun, ninu ifẹ Rẹ̀ fun gbogbo ẹda eniyan, sọ nipa ti ogo Ijọba Ọrun naa lọpọlọpọ fun awa eniyan. Ibi pupọ ninu Ọrọ Rẹ̀ ni a sọ nipa eyi lati fi hàn bi o ti ṣe iyebiye to. Awọn wolii Majẹmu Laelae yọ, gẹgẹ bi a ti kọ́ sinu awọn ẹkọ wa ti iṣaaju, nipa iran ti a ṣi paya fun wọn ni ti Ijọba ti a ṣeleri ti ko si le rekọja, nibi ti ko ni si ibanujẹ, ẹkún ati ikú; nibi ti Ọba ododo yoo gunwa lori itẹ Dafidi; Bi a ba si lọ wo Majẹmu Titun a o ri i pe Ijọba yii jẹ ọ̀kan pataki ninu ohun ti a sọrọ rẹ̀. Johannu Baptisti kede rẹ̀, nitori Ọba naa tikara Rẹ̀ de nikẹyin. Nigba ti Jesu si bẹrẹ iṣẹ iranṣẹ Rẹ̀, O kigbe bakan naa gẹgẹ bi òléwá Rẹ̀ pe, "Ẹ ronupiwada: nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀," O si kọ ni nipa ohun iyanu ti Ijọba Rẹ̀, eyi ti awọn wolii wadii, ti awọn angẹli si n fẹ lati ri. O gbe Ijọba naa ga to bẹẹ, ati pe o ṣe ohun danindanin lati de ibẹ, to bẹẹ gẹẹ ti ko fi si ohun ayé yii kan ti a le fi ṣe odiwọn rẹ̀. Ninu Iwaasu lori Oke O

rọ awọn ọpọ eniyan pe, “Ẹ maṣe ṣe aniyan, wipe, Kili a o jẹ? tabi, Kili a o mu? tabi, aṣọ wo li a o fi wọ̀ wa? (Nitori gbogbo nkan wọnyi li awọn Keferi nwá kiri:) nitori Baba nyin ti mbẹ li ọrun mọ̀ pe ẹnyin kò le ṣe alaini gbogbo nkan wọnyi. Ṣugbọn ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ̀; gbogbo nkan wọnyi li a o si fi kún u fun nyin,” (Matteu 6:31-33). “Nitori Ijọba Ọlọrun ki iṣe jijẹ ati mimu; bikoṣe ododo, ati alafia, ati ayọ̀ ninu Ẹmí Mimọ́” (Romu 14:17).

Ṣugbọn pẹlu gbogbo ohun ti Ọrọ Ọlọrun kọ́ ni nipa Ijọba Ọrun, oye ọmọ eniyan ko le mọ titobi rẹ, bẹẹ ni oju ti ode ara ko le ri ogo rẹ. “Ohun ti oju kò ri, ati ti etí kò gbọ, ti kò si wọ ọkàn enia lọ, ohun wọnni ti Ọlọrun ti pèse silẹ fun awọn ti o fẹ ẹ. Ṣugbọn Ọlọrun ti ṣi wọn paya fun wa nipa Ẹmí rẹ̀” (1 Kọrinti 2:9, 10). Onisaamu si kigbe pe, “Tọ́ ọ wò, ki o si ri pe, rere ni Oluwa” (Orin Dafidi 34:8). Lẹyin naa jẹ ki ẹni ti o fẹ mọ siwaju si i nipa Ijọba Ọrun wá ni ironupiwada tootọ ki o si gbadura agbayọri titi oun yoo fi mọ pe a dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i, a si kọ orukọ rẹ̀ silẹ ni Ọrun. Oju rẹ̀ ti ẹ̀ṣẹ ti fọ́ yoo là, oun yoo si ri ohun gbogbo ti ko ti mọ tẹlẹ ri. Oun yoo ri “iṣura ti a fi pamọ́ sinu oko,” ṣiṣe iyebiye rẹ yoo si mu ki oun naa pẹlu lọ ta “ohun gbogbo ti o ni,” ki o ba le ni iṣura yii. Bi oun yoo ba si “kọ ohun gbogbo silẹ,” iṣura naa yoo jẹ́ ti rẹ̀.

**Perli Olowo Iyebiye**

Owe yii sọ siwaju sii nipa ohun ijinlẹ Ijọba naa, nitori Ọba tikara Rẹ̀ ni o n bawi, gẹgẹ bi a ti gbagbọ́. Lẹyin gbogbo rẹ̀, ohun gbogbo ti o ba jẹ ti Ijọba, lọdọ Rẹ̀ naa ni o ti wá. Lai si ọba ko le si ijọba, ati pẹlu, a ko le ni ipa kan tabi ipin ninu ijọba yii, afi bi a ba ni Ọba naa, eyi ti i ṣe “Kristi ninu nyin, ireti ogo.” A ko le ya Jesu kuro lara Ijọba Ọrun, nitori Bibeli kọ ni pe idapọ nla kan wà laaarin Jesu ati Ijọba Rẹ̀, ti aye ati ọba rẹ ko mọ̀ ti ko si le wọ̀. Nitori naa ni Jesu ṣe sọ fun baalẹ ara Romu ni pe, “Ijọba mi ki iṣe ti aiye yi” nitori Oun funra Rẹ̀ ki i ṣe ti ayé yii. Iba diẹ ni a le kiyesi nihin nipa ibarẹ ti o wà laaarin Jesu ati Ijọba Rẹ̀.

**Ekinni**

Ijọba Ọrun, Ijọba ayeraye ni i ṣe, nitori Ọba rẹ jẹ Ọmọ Ọlọrun ayeraye gẹgẹ bi Bibeli ti wi: “Ṣugbọn mo ti fi ọba mi jẹ lori Sioni, òke mimọ́ mi. Emi o si rohin ipinnu OLUWA: O ti wi fun mi pe, Iwọ li Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ” (Orin Dafidi 2:6, 7). Ọrọ rere ti a sọ nipa Ọlọrun ninu Orin Dafidi 45:6, 7 ati 102:25-27, ohun kan naa ni Paulu Apọsteli sọ nipa Ọmọ ninu Iwe rẹ̀ si awọn Heberu bayii pe: “Ṣugbọn niti Ọmọ li o wipe, Itẹ́ rẹ, Ọlọrun, lai ati lailai ni; ọpá alade ododo li ọpá alade rẹ. Iwọ fẹ ododo, iwọ si korira ẹ̀ṣẹ; nitorina li Ọlọrun, ani Ọlọrun rẹ, ṣe fi oróro ayọ̀ yan ọ jù awọn ẹgbẹ rẹ lọ. Ati Iwọ, Oluwa, li atetekọṣe li o ti fi ipilẹ aiye sọlẹ; awọn ọrun si ni iṣẹ ọwọ́ rẹ: Nwọn ó ṣegbe; ṣugbọn iwọ ó wà sibẹ, gbogbo wọn ni yio si gbó bi ẹwu; Ati bi aṣọ ni iwọ o si ká wọn, a o si pàrọ wọn: ṣugbọn bakanna ni iwọ, ọdún rẹ kì yio si pin” (Heberu 1:8-12).

**Ekeji**

Ijọba agbara ni o jẹ́, ti o si ga ju gbogbo awọn ijọba miiran lọ, gẹgẹ bi awọn ẹkọ ti a ti kọ́ sẹyin ti sọ fun ni, nitori gbogbo agbara ni a fi fun Ọba naa, gẹgẹ bi Jesu ti sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lẹyin ajinde. “Jesu si wá, o si sọ fun wọn, wipe, gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a fifun mi” (Matteu 28:18). A si tun fi agbara yii hàn siwaju si i nipa ọna ti Oun o gba ṣakoso awọn orilẹ-ede nigba ti o ba pada wá si ayé: “Ọpá irin ni iwọ o fi fọ́ wọn; iwọ o si rún wọn wom-wom, bi ohun èlo amọ̀” (Orin Dafidi 2:9).

**Ẹkẹta**

Ijọba ododo ni i ṣe, nitori Ọba naa jẹ olododo gẹgẹ bi iwe Mimọ́ ti a kọ soke. “Itẹ́ rẹ, Ọlọrun, lai ati lailai ni; ọpá alade ododo ni ọpá alade ijọba rẹ. Iwọ fẹ ododo, iwọ si korira ẹṣẹ; nitorina ni Ọlọrun, ani Ọlọrun rẹ, ṣe fi oróro ayọ̀ yan ọ jù awọn ẹgbẹ rẹ lọ.”

**Ẹkẹrin**

Ijọba iyè ni, ani **iye ti ko nipẹkun** ni i ṣe pẹlu, gẹgẹ bi o ti fi han nipa iyipada ọkàn ti o n ṣẹlẹ ni ayé isisiyii ati ileri nla ti ajinde oku ti o wà niwaju awọn ẹni-irapada Oluwa nitori Ọba tikara Rẹ̀ jẹ Ajinde ati Iye: “Jesu wi fun u pe, Emi ni ajinde, ati ìye: ẹniti o ba gbà mi gbọ́, bi o tilẹ kú, yio yè” (Johannu 11:25). “Eyi si ni ifẹ ẹniti o rán mi, pe ẹnikẹni ti o ba wò Ọmọ, ti o ba si gbà a gbọ́, ki o le ni iye ainipẹkun: Emi ó si ji i dide ni ikẹhin ọjọ” (Johannu 6:40).

**Ẹkarun-un**

“Awọn ọmọ ijọba” ti a bi nipa ti Ọlọrun maa n wà ni irẹpọ pẹlu Ọba naa, wọn si ni lati dabi Rẹ̀: “Ẹ wo irú ifẹ ti Baba fi fẹ wa, ti a fi npè wa ni ọmọ Ọlọrun; bẹ li a sa jẹ. Nitori eyi li aiye kò ṣe mọ̀ wa, nitoriti ko mọ̀ ọ. Olufẹ, ọmọ Ọlọrun li awa iṣe nisisiyi, a kò si ti ifihan bi awa ó ti ri; awa mọ pe, nigbati a bá fihan a ó dabi rẹ̀; nitori awa o ri i, ani bi on ti ri. Olukuluku ẹniti o ba si ni ireti yi ninu rẹ̀, a wẹ̀ ara rẹ̀ mọ́, ani bi on ti mọ́” (1 Johannu 3:1-3).

Nitori naa a gbagbọ pe “perli olowo iyebiye” yii ni Ọba naa. “Ọkunrin” onișowo kan ti o si n wá perli ti o dara,” ni ọkunrin naa ti o ti ri idi ohun ti o wà ninu Perli olowo iyebiye naa, ó si wọ̀ ọ́ lọkan to bẹẹ, ti o fi yara lọ ta ohun gbogbo ti o ni, o si ra a.

Paulu Apọsteli jẹ ọkunrin “onișowo miran kan ti o n wa perli ti o dara,” ti o si ri iran Perli olowo iyebiye naa lọna ajo rẹ si ilu Damasku. Oun naa lọ, o si ta “ohun gbogbo ti o ni” ki o ba le ni Perli naa. Nigba ti a si fi i sinu ọgbà ẹwọn ni Romu, o sọ diẹ fun ni nipa iriri rẹ bi oun ti ṣe le ṣe bẹẹ:

**“Ohunkohun ti o ti jasi ère fun mi, awọn ni mo ti kà si òfo nitori Kristi. Nitõtọ laiṣe ani-ani mo si kà ohun gbogbo si òfo nitori itayọ imọ Kristi Jesu Oluwa mi: nitori ẹniti mo ti ṣòfo ohun gbogbo, mo si ka wọn si igbẹ́, ki emi ki o le jère Kristi, ki a si le bá mi ninu rẹ̀, li aini ododo ti emi tikarami, ti o ti inu ofin wá, ṣugbọn eyi ti o ti inu igbagbọ́ wá ninu Kristi, ododo ti Ọlọrun nipasẹ igbagbọ: Ki emi ki o le mọ̀ ọ, ati agbara ajinde rẹ̀, ati alabapin ninu iya rẹ̀, nigbati mo ba faramọ ikú rẹ̀; bi o le ṣe ki emi ki o le de ibi ajinde awọn okú” (Filippi 3:7-11).**

Ọdun pupọ lẹyin iriri rẹ ni Damasku, Paulu jẹri niwaju Agrippa, o si pari ọrọ rẹ bayii pe “Nitorina, Agrippa ọba, emi kò ṣe aigbọran si iran ọ̀run na.” Ẹri ikẹyin ti ọmọ-ogun Agbelebu yii nigba ti o n reti iku rẹ fi han pe o gbọran si “iran ọ̀run na” titi de opin:

**“Nitori a nfi mi rubọ nisisiyi; atilọ mi si sunmọ etile. Emi ti jà ìja rere, emi ti pari ire-ije mi, emi ti pa igbagbọ́ mọ́: lati isisiyi lọ a fi ade ododo lelẹ fun mi, ti Oluwa, onidajọ ododo, yio fifun mi li ọjọ na, ki si iṣe kìki emi nikan, ṣugbọn pẹlu gbogbo awọn ti o ti fẹ ifarahan rẹ” (2 Timoteu 4:6-8).**

Owe meji wọnyi ti a ti n kọ bọ kọ wa pe ẹni ti yoo ba wọle Ijọba Ọrun ki o si duro niwaju Ọba nigba ti Oun ba de, ni ohun pataki lati fi silẹ. Ni ọjọ ipalẹmọ Rẹ̀ yi, Oun n ṣe iṣẹ aṣepe Rẹ̀ lọ laarin awọn ọmọ Ijọba naa lati mu wọn yẹ fun ile ọrun. Bi ẹni kan yoo ba si ni Perli olowo iyebiye yi, ki o si gba “ade ododo” nikẹhin ọjọ, o gbọdọ lọ ta ohun gbogbo ti o ni.

**“Jẹ ki n lọ jina ’nu ifẹ Jesu**
**Ni ojoojumọ**
**Ki n tẹsiwaju, ’nu ẹkọ**
**Ki n ni ore-ọfẹ si i.**
**“Ẹmi Mimọ́, ri mi sinu ’bu rẹ,**
**Wá kun ọkan mi,**
**Ki gbogbo aye mi jẹ ti Jesu**
**Lati ṣe ifẹ Rẹ̀.”**

**Àwọ̀n Ẹja**

Nigba ti Jesu n sọ asọtẹlẹ ọjọ ikẹyin, O wi pe “A o si wasu ihinrere ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹri fun gbogbo orilẹ-ède, nigbana li opin yio si de” (Matteu 24:14). A gbagbọ pe asọtẹlẹ yii fara mọ owe pataki ti àwọ̀n apẹja yii; eyi ni pe “àwọn ti a sọ sinu okun,” ni Ihinrere ti Ijọba yii, “okun” si ni ọpọlọpọ eniyan laaarin orilẹ-ède gbogbo ti a n waasu Ihinrere fun. Àwọ̀n naa “kó onirũru gbogbo; nigbati o kún, eyi ti wọn fà soke, nwọn joko, nwọn si kó eyi ti o dara sinu agbọ̀n, ṣugbọn nwọn kó buburu danù,” o jẹ aṣa ti o wọpọ laaarin awọn apẹja ọmọ-ẹyin Jesu, a o si ri i pe o jẹ apẹẹrẹ ohun ti o n ṣẹlẹ ninu iṣẹ Ihinrere.

Ikede Ihinrere ni ayé oore-ọfẹ yii ti fa eniyan buburu ati eniyan rere wa. Ki i ṣe gbogbo “ẹja” ti a mú ninu àwọn ni o n pada di rere. Ni ọjọ wọnni paapaa, nigba ti Oluwa mu awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni ilẹ Egipti, “awọn adalu eniyan” palẹ ohun ini wọn mọ́, wọn si ba wọn jade nitori ibukun Oluwa wà lori Israẹli. Awọn adalu eniyan wọnyii pagọ ti wọn lẹyin ibudo, awọn ni o si fa wahala ati ijọngbọn wa ba Israẹli eyi ti i ṣe arekereke eṣu lati di iṣẹ Oluwa lọwọ. Bakan naa ni “awọn ọmọ ijọba” maa n ni awọn “alakowaba” ti wọn -- awọn eniyan ti o dara pọ mọ Ijọ, ti “wọn si wi pe Ju ni awọn ti wọn ki si i ṣe bẹ.” Awọn ẹgbẹ yii ni Jesu n bawi pe, “Ki iṣe gbogbo ẹniti npè mi li Oluwa, Oluwa, ni yio wọle ijọba ọrun, bikoṣe ẹniti nṣe ifẹ ti Baba mi ti mbẹ li ọrun. Ọpọlọpọ enia ni yio wi fun mi li ọjọ na pe, Oluwa, Oluwa, awa ko ha sọtẹlẹ li orukọ rẹ? ati orukọ rẹ ki a fi lé awọn ẹmi èṣu jade? ati li orukọ rẹ ki a fi ṣe ọ̀pọ iṣẹ iyanu nla? Nigbana li emi o si jẹwọ wi fun wọn pe, Emi kò mọ̀ nyin ri, ẹ kuro lọdọ mi, ẹnyin onișẹ ẹ̀ṣẹ” (Matteu 7:21-23).

Bẹẹ si ni ọjọ kan n bọ wa ti ipinya yoo de, nigba ti a o kó “ẹja rere” sinu agbọ̀n, ṣugbọn “ẹja buburu” li a o kó danu. “Gẹgẹ bẹ̃ni yio si ri ni igbẹhin aiye: awọn angẹli yio jade wá, nwọn o yà awọn enia buburu kuro ninu awọn olõtọ, nwọn o si sọ wọn sinu iná ileru; nibẹ li ẹkún on ipahinkeke yio gbé wà.” Ṣugbọn ni akoko yii, o yẹ ki “awọn

ọmọ ijọba” ki o pa aṣọ wọn mọ ni ailabawọn, ki wọn si ri i pe ko si ẹkọ eke kan ti ó wà lode ti yoo wọ ọkàn wọn. “Kiyesi i, emi mbọ̀ nisisiyi: di eyiti iwọ ni mu ṣinṣin, ki ẹnikẹni ki o máṣe gbà ade rẹ” (Ifihan 3:11).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni iṣura ti a fi pamọ́ sinu oko duro fun?
2. Ipo wo ni ọkunrin naa wa nipa ti ẹmi nigba ti o ri i?
3. Ki ni ọrọ wọnyii jẹ́ fun Onigbagbọ: o “lọ o si ta ohun gbogbo ti o ni”?
4. Ki ni “perli olowo iyebiye” duro fun?
5. Ki a wo gẹgẹ bi Onigbagbọ, ta ni “ọkunrin oniṣowo kan ti o n wá perli daradara”?
6. Ki ni ṣe ti awọn ọmọ-ẹyin ni oye ohun ijinlẹ Ijọba naa ju ọpọ eniyan lọ?
7. Ki ni “àwọn ti a sọ sinu okun” duro fún?
8. Iwe Mimọ́ wo ni apẹẹrẹ yii bá lọ?
9. Ki ni “okun” duro fun?
10. Ki ni “ẹja rere” ati “ẹja buburu” duro fún?